# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 862 LAGOS SARTUDAY MARCH 30 — APRIL 5 1963 KỌBO MEJI (2D)


Sangba Fo!

# Oba Ilu Kano Binu Fade Sile Lori Oro Ilu Olopa'nu Mu Alkali Kano Paapa

KANO—Sangba fo! Waya irohin pajawiri kan ti a ri gba ni oru ana lati ọdọ akọwe irohin wa ni Kano ni Ipinle Ariwa ni ti Ọlọla Alhaji Muhammadu Sanusi, Ọba ilu Kano ti o binu fi Lawani ori rẹ silẹ, o ni on ko jọba awọn Hausa mọ.

Irohin pato ti a gbọ lori ọrọ na ni wipe ede aiyede kan ti wa larin Ọba Kano pẹlu Ijọba Ipinlẹ Ariwa lori ọrọ inawo Ijọba ibilẹ ilu Kano ti Ọba na nṣe alaga rẹ ti pẹ. Awọn alamojuto Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni bi awọn olori ti nwọn wa nidi eto Ijọba Ibilẹ ilu na ti nṣe nna

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

KANO—Lori ọrọ iwadi (ẹnkuari) Ijọba Ibilẹ Kano yi awọn ọlọpa'nu Kano ti mu Alkali Danbata Mallam Muhammmadu Darma fun ẹsun wipe o lọ ba Hausa olori Abule kan, Mallam Mahammadu Lawan, o ndẹ ruba a wipe on yio jẹki ọba Kano yọ ọ kuro loye nitori eri buburuku ti o jẹ nigbati nwọn nṣe iwadi (ẹnkuari) lọ

(Wo i oku loju ewe kẹjọ)



GOMINA-AGBA NI ILE IGBIMỌ

## Ijoba Apapose Bere Ipade Igbimo L'eko

EKO--Ni owurọ Ọjọ'Ru tiṣe ọjọ ketadinlogun oṣu yi ni Ijọba Apapọse bẹrẹ ipade wọn ni ile Igbimọ l'Eko. Gomina-agba Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe ni o si ṣi ipade na fun wọn.

Ki Gomina-agba to wọ mọto-ayọkẹlẹ de pẹlu iyawo rẹ, Flora, ẹsẹ gbogbo awọn enia jankan jankan ti nwọn wa wo iran pẹlu awọn ikọ ti nwọn wa lati orişirişi ilu kakiri ti pe sibe şiba şiba pẹlu Ọgbẹni Olori awọn jagunjaguu ilu Congo, Mobutu, ti o ṣẹṣẹ de si ilu pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ mẹfa ati iyawo rẹ. Gomina-agba si wọ aṣọ bi ọga awọn ṣoja-ologun.

Gbara ti o ti bọ silẹ ninu moto rẹ ti o si ti bẹ awọn soja ti nwọn to lọwọ lọwọ fun eyẹ ọjọ na wo tan ni o tẹ wọ ile Igbimọ na lọ lati ba gbogbo awọn ikọ sọrọ nipa gbogbo eto awọn nkan mere-mere ti awọn alakoso Ijọba Apapọṣe fẹ ṣe fun ilu Nigeria ninu ọdun ti a fẹ bọ si yi.

( Wo iyoku loju ewe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

An Extraodinary General Meeting of the Lagos Race Club will be held at the Members Enclosure, Race Course, on Thursday 4th April, 1963 at 5.30 p.m. Members should please note that admission will be by production of badges only.

AGENDA:

1 Revision or Amendment of Club Rules.
2 Any other business.

C.H.E. MILLER
Hon. Secretary.

## Awon Onisowo Ijaw Ni Ki Ijoba Ju Awon Sile Pelu Oti-Bolugi

WARRI—Awọn kan ti nwọn pe ara wọn ni ẹgbẹ onişowo ilu Ijọ (Ijaw) ni Warri tl kọwe-ẹbẹ ranşẹ si Gomina-Agba Ọlọla Dokita Nnamdı Azikiwe wipe ki o jẹ awọn fi orişa ilu awọn bẹ ẹ, ki o ba awọn fi ọrọ si i, ki awọn olutu Ijọba Apapọşe le tun ofin ọti pipọn şe, ki nwọn jẹ ki awọn mışe ỌTI-BỌLUGI ni ita gbangba, ki awọn si mą ta a ni şọbu kakiri bi ti awọn oyinbo.

Nwọn ni awọn şẹ akiyesi ninu ọrọ Gomin-agba na nigbati o mba awọn Igbimọ aşofin sọrọ ninu ọdun ti o kọja, ti o ni Ijọba yio şe ofin lori ọti-bọlugi ti nwọn yio fi ma ri owo mu wọle si apo Ijọba lori rẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ni inu awọn si dun pupọ lori ọrọ yi. Nwọn ni gbogbo awọn ọmọ Ijaw ati Urhobo ti nwọn npọn ọti na ni inu wọn dun si i.

Nwọn ni bi Ijọba ba le fun awọn laiye lati mọ şe ọti yi ni gbangba dipo bonkẹle ti awọn nşe e owo yio mọ wọle fun Ijọba apapọşe.

Akọwe wọn ti nwọn npe ni Fredrick Agugu ni o fọwọ si iwe na.

## Mobutu Balogun Congo Wa We Nigeria

EKO—Joseph Mobutu tişe Balogun awọn şọja ilu Congo de si Eko ni ijẹta lati wa bẹ ilu Nigeria wo, nigbati o mbọ, o mu iyawo rẹ lọwọ pẹlu awọn amugbalẹhin rẹ mẹfa ninu awọn ọmọ ogun ilu wọn.

Gbara bi ọkọ ofurufu ti o wọ ti gunlẹ ni Ikeja ni awọn akọwe oniwe irohin ti su-ru mọ ọ lati gba ọrọ lẹnu Balogun Mobutu na nipa bi nkan ti nlọ si lọri ọrọ ilu wọn. Balogun na ni on fẹ ki nwọn mọ wipe ọga şọja ni on, on kişe oşelu rara nitorina on ko le sọ nkankan nipa ọrọ ilu.

O tun şe alaye wipe eyi ni igba kinni ti on yio kọ wa si Nigeria, şugbọn o n ş e iranti igbati on lọ si Brussels, Kanọ ni awọn gba lọ.

Ọgbẹni Mobutu ni on kan saara si awọn şọja ilu Nigeria ti o wa ni ilu awọn nitoripe g b o g b o wọn ni nwọn n ş i ş ẹ ribiribi lọhun.

O ti lọ si Kaduna nisisiyi, ki o to pada si Congo a de Ibadaan ati Enugun.




GET AROUND BETTER-TRAVEL

lambretta

2nd SERIES 150 Li ........ £145
'SLIMSTYLE' 150 Li ........ £162
'SLIMSTYLE' 175 Tv ........ £175

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (S.B.) • IBADAN • KANO • KADUNA • JOS • PORT HARCOURT • ABA

### Awon Alhaji Onimodaru:

# Opolopo Awon Ero Ti Nmura Meka Nisisiyi

EKO — Ọpọlọpọ awọn enia lọkunrin ati lobinrin ti nwọn nfẹ lọ si ilu Mẹka (Mecca) ati Mẹdina ni ọdun yi ni nwọn ti npalẹmọ kiakia, ogunlọgọ wọn ni nwọn si ti kọ namba lọdọ awọn alaṣẹ imọtoto.

Ni Ibadan, ni ipinlẹ Ijọba Iwọ Orun, ojojumọ ni awọn ero ti o fẹ lọ si Mẹka nwọ ni ile ibiṣẹ ti nwọn nṣe eto fun awọn Imale ti nwọn fẹ rin irin-ajo na. Ni ana nigbati akọwe onirohin wa de ile iṣẹ na, o ri on ri ọpọlọpọ enia ti nwọn wa lati ilu bi Abẹokuta, Ọtta, Ijẹbu-Ode, Iwo, Ọyọ, Ẹdẹ, Oshogbo, Ogbomọshọ ati Iṣẹyin.

Mo gbọ wipe iru ile iṣẹ bayi ti nwọn da silẹ ni Kaduna ni awọn ara Ilọrin ti nwọn fẹ lọ si irin-ajo Mẹka nlo. Lati ẹnu ọsẹ keji lọhun ni iṣẹ awọn akọwe ile iṣẹ awọn ero na ti bẹrẹsi pọ si.

Onirohin wa kan lati Iu Dahomey sọ fun wa wipe gbogbo awọn ara Ajaṣẹ paapa ti nwọn fẹ lọ si Mẹka ti mu ra tan; a gbọ wipe ọpọlọpọ wọn ni Kutọnu (Cotonou) ni nwọn yio ti wọ ọkọ ofurufu ti nwọn wa si Eko, awọn ara Ivory Coast lati Abidjan paapa mbọ wa.

## Egbe Alaji

Irohin ti a tun gbọ nipa ti awọn Alhaji na ni ti ẹgbẹ kan ti nwọn da silẹ ti nwọn npe ni Zumratul—Majaj. Awọn ẹka ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun ti fi iwe-ebẹ sọwọ si awọn alaṣẹ Ijọba wipe ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn ko de ilu Mẹka ri lo nsin awọn jẹ, ti nwọn nde FILA ALAJI bi awọn.

Nwọn ni aṣa na ko ba oju mu rara, ki awọn alakoso Ijọba gba awọn ki nwọn ba awọn ṣe ikilọ fun wọn nitoripe nwọn nṣe aṣa na lati tan awọn obinrin jẹ ni. Alhaji L. B. Ishọla ni Ibadan, ni o fọwọ si iwe na.

### Awon Iwe Asiko:

# Ede Yoruba Dun Ka

(Lati ọwọ AKỌWE)

Ni ọsẹ ti o kọja mo da ẹda ọrọ AṢARO kan jade ninu ọkan ninu IWE IKILỌ FUN AWỌN ỌDỌ ti Alufa (Rev.) E.A. Atilade tẹ jade ninu ọgọrọ awọn iwe ti o kọ fun awọn ọmọ ile iwe ati awọn agbalagba ti o fẹ kọ ọgbọn lọjojumọ.

Nwọn ni ojojumọ ni enia nma kọ'gbọn ati pe gẹgẹbi ọrọ aṣaro ti a fa yọ ninu ọkan ninu iwe na ni ọsẹ yi o ni ki a ma kọja aye wa ninu ipo ki po ti a ba wa:

MA KỌJA AYE Ẹ

1 Ma kọja aye ẹ,
Bo ti wu k'o ni 'po to,
O ni 'biti ipo rẹ mọ;
B'o ba wa niwaju l'agbo kan,
O le jẹ ọmọ-ẹhin l'agbo miran.

2 Ma kọja aye ẹ,
Bo ti wu k'o gbọn to,
O ni 'biti ọgbọn rẹ mọ;
B'o ba j'ọlọgbọn l'agbo kan,
O le jẹ ope l'agbo miran.

3 Ma kọja aye ẹ,
Bo ti wu k'o l'ewa to,
O ni 'biti ewa rẹ mọ;
B'o ba j'ẹlẹwa l'agbo kan,
O le j'obuwewa l'agbo miran.

4 Ma kọja aye ẹ,
Bo ti wu k'o ni aṣẹ to,
O ni 'biti aṣẹ rẹ mọ;
B'o ba jẹ alaṣẹ l'agbo kan,
O le j'ọmọ 'ransẹ l'agbo miran.

5 Ma kọja aye ẹ,
Bo ti wu k'o l'agbara to,
O ni 'biti agbara rẹ mọ;
B'o ba jẹ alagbara l'agbo kan,
O le jẹ alailagbara l'agbo miran.

Bi enia ba nle ka awọn aṣaro ọrọ yi lẹsẹsẹ ni wurẹ, ti o ba ti ii ki o to gba ibi iṣẹ Ọọjọ rẹ lọ ko ni se igberaga si ẹnikẹni, yio si ma gba ayi at eje lọdọ ebi ati ọrẹ pẹlu awọn aladugbo rẹ.

Nitotọ, a ri i ka ninu iwe Mimọ pe igberaga ni saju iparun; ọpọlọpọ ni iwa-igberega na ti ba igbesi aiye wọn jẹ lode oni lọkunrin ati lobinrin

### Davey Moore Elese Ku:

## Gomina Kan Ni ON Ko Fe Ere Ese Mo Ni Ilu On

LOS ANGEL (U.S.A.)—Iku ọdọmọde ilu Amerika elere ẹṣẹ kan ti orukọ rẹ njẹ Davey Moore, ẹni ọdun mọkandinlọgbọn, ti o jalaisi ninu ile alaisan ni ọjọ kẹrin ti on ẹnikan ti nwọn npe ni Sugar Ramos ara ilu Kuba (Cuba) ti ja ija ije ẹṣẹ, fẹ da ruke rudo silẹ larin awọn elere ẹṣẹ jija kakiri agbaiye nitoripe Gomina ilu kan ti fi aake kọri nisisiyi wipe on ko fẹ ere janduku na ni ilu on mọ.

Ni Ọjọ'Bọ (ọjọ Alamisi) ijẹsan ni Ologbe Davey Moore tiṣe olori awọn ẹlẹṣẹ ti nwọn npe ni featherweight fi aga-gbaga pẹlu Sugar Ramos ti o fọ ọ lori yi. Tẹlẹtẹlẹ Ọgbẹni Hogan Bassey ọmọ ilu Nigeria ni o ti nṣe olori wọn ki Moore to gba ni ọwọ rẹ ni ọdun kẹrin sẹhin ki Bassey paapa to fidi mọlẹ nile. Awọn eniakan ni o ba Bassey damọran wipe eyi ti o ṣe ninu ere ẹṣẹ jija to.

Irohin ti a gbọ lati ilu ti nwọn ti ja ẹṣẹ ti o ran Davey Moore lọ ọrun apapandodo na ni pe Gomina Edmund Brown ni on a da a ni imọran fun awọn aṣofin ilu on wipe ki awọn se ofin ki nwọn ye ja ẹṣẹ ni ilu awọn.

(wo yoku ni oju ewe kẹfa)

### OKU 'BINRIN KAN BỌMỌ NI ILU OYINBO

Washington (U.S.A.)—Oju a ri to ninu aiye ti a wa yi; irohin nla kan ti o jẹ a-gbọ-yanu ni ti obinrin Oyinbo kan ti orukọ rẹ njẹ Maudine Tethan ti o ku bamu bamu nibiti o gbe ngbe, obinrin na si loyun sinu.

Nigbati awọn aladugbo ri pe obinrin na ku, were nwọn ti ranṣẹ si awọn dokita ti o wa ni adugbo wọn. Awọn dokita ko fi ikan pe meji, iṣẹ abẹ ni nwọn ṣe fun obinrin na, nwọn si gba ẹbi fun un.

Ọmọ jankulubọ ti o bi na tẹ iwọn pupọ, ara rẹ si da bi kaun, ko si amodi kan ra rẹ.

# ELETI—OFE

A NJUWKO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 861 SATURDAY MAR. 30- APRIL. 5 1963


# Onje Ni Ore Awo....

Awọn Yoruba ni orişirişi ọrọ işiri ti o ba nkan ti nwọn ba nşe lọwọ inu. Ni ilẹ Yoruba bi agbẹ ba gbin işu si oko tabi nkan ọgbin miran bi ẹgusi tabi ila ti nwọn si yọ daradara, ti o ba ko wọn de le, inu awọn iyawo rẹ yio dun lati se ọbẹ ti o dọsọ fun un, ti on na ba si jẹ iyan tan, ti o joko sidi ọpan ayo pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ, on na a ma da'para wipe ONJẸ NI ỌRẸ AWỌ.

Nitotọ tani yio sọ wipe on ko mọ wipe ONJẸ NI ỌRẸ AWỌ. Ni ijẹta ni awọn ẹgbẹ Igbimọ agbaiye fun idẹra bẹrẹsi se ikede OMINIRA KURO NINU ebi (Freedom from hunger). Nwọn ni ọpọlọpọ awọn enia ni o wa ni aiye nisisiyi ti ebi npa.

Awa oniwe irohin Eleti—Ọfẹ ni nitotọ ni ọrọ wọn nitoripe a se akiyesi ọpọlọpọ nkan ti a fi mọ wipe ebi npa ọmọ araiye, diẹ si ni eyi ninu awọn nkan na:

Ikinni ojojumọ ni awọn ọmọ araiye mbi ọmọ si, ọna ti a si fi mbi awọn ọmọ na pọ ju ti atijọ lọ. Bi a ko ba bi ibeji, a bi ibẹta tabi o fi de ibẹrin. Ọmọ ọdun mẹtala mbi ọmọ ni aiye ode isisiyi.

Ọna keji, gbogbo Ijọba agbaiye ni nwọn nd de si ara wọn; kaka ki nwọn na owo lori eto bi awa ọmọ araiye yio se ri nkan je, lori nkan ija ogun ni nwọn nna owo iyebiye le lori lojojumọ.

Ki a ti ibi işana kiye si etu, awa ara Nigeria paapa ti a şeşe gba ominira lọwọ ni owo ti a nna lori awọn soja ati ọlọpa nitoripe iwa wa ni o mba wa lẹru. Şe iwa ọmọ ni o nmu ọmọ şe ogun okigbẹ.

Ọna kẹta, ko si ẹniti o fẹ se işẹ agbẹ mọ bi'ti'awọn baba wa ni aiye atijọ. Gbogbo wa ni a fẹ ma se işẹ-owo, ni a fe di lọya, a fẹ di akọwe oni kọla lọrun, ki a mọ ọ ninu mọto ayọkẹlẹ. Nitotọ onjẹ ni ọrẹ awọ.

# Iwe Si Olotu

## Otito Oro Bi Isokuso

Mo gba fun ọrọ ti ẹ sọ ni aipẹ yi nipa ti owo-ile ti awa Ẹgbẹ fi igba kan fi aake k'ọri wipe a ko ni san ti a si wa nsan diẹ diẹ nisisiyi.

Nitotọ nigbati nwọn kọ gbe mọran owo-ile na jade fun wa ọrọ ẹtan ti awon kan sọ wipe oko-ẹru ni nwọn fẹ mu wa lọ ni o jẹ ki a kọ ọ, a ko mọ wipe ire awa ọmọ Ẹgbẹ ni nwọn wa.

Ọlọrun ma jẹ ki eni iwaju ki o di ero ẹhin. Otitọ ọrọ bi isọkusọ ni o nri.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi,

Emi ni,
Eko Ọladimeji Adisa

Emi alara paapa ti ngburo iwe Alufa ATILADE ti pẹ. Mo giran wipe on ni o kọ iwe kan ti nwọn npe ni YORUBA DUN KA fun awọn ọmọlewe ti nwọn şẹ şe bere iwe kikọ nigba kan.

Inu wa yio dun pupọ ti ẹ ba nle ma tẹ awọn iwe Yoruba ti awọn kan ba şe şe tẹ jade fun wa nigbagbogbo.

Ojo-Oniyun Emi ni,
Ebute-Metta J. Ọladele

## Ede Yoruba Dun Ka . . .

Olotu, ẹ jowọ ẹ gba mi laye lati kan sara si AKỌWE fun awọn eda ọrọ Aşaro ti o tẹ jade fun wa ninu awọn IWE ASIKO ti Alufa ATILADE kọ.

## Ere Ese jija

Bi ere esẹ jija tişe di orişa kekere a-kunlẹ-bọ ni ilu awọn Oyinbo Amẹrika ni ọrọ ti ẹ o gbọ lati ọdọ OLOFINTOTO ELETI-OFẸ ni ọsẹ ti mbọ. OLOFINTOTO wa na şeşẹ ti irin ajo kan de lati Ipinlẹ Ariwa ni...

—Olotu

## SYMBOLS OF POWER



This striking photograph contrasts the classical simplicity of a Rolls-Royce car radiator, which has long been recoginised the world over as a symbol of top quality British engineering in the field of high-powered motor cars

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## (Lati Owo Ayiluka)

### Ile Igbimo

Emi Ayiluka ki ẹyin ọkawe mi pe ẹ ku suru iregbe mi ti mo nṣe fun yin ni ọsọsẹ. Ni ọsẹ'yi ọrọ mi ko ni pọ ṣugbọn nwọn a mu ọgbọn dani. Emi na ba wọn ṣe oju-mi-to lọ si ile-igbimọ awọn aṣofin fun ipade wọn ti nwọn bẹrẹ ni ijẹrin l'Eko.

Ẹnyin ara mi, ṣe ki nsọ ọrọ tọtọ fun yin? Ninu Ile-igbimọ Apapọṣe Ijọba ilẹ Nigeria ko si awọn alatako mọ nibẹ. Ti ọrọ mi ba dabi irọ ti ẹ ba raiye ki ẹ lọ si Ọdan ki ẹnyin na lọ wo bi awọn ikọ wa ti nṣe aiye si.

Ọna ti alatako ṣe le wa da? Ọmọ ẹgbẹ olomi ti dapọ mọ ọmọ ẹgbẹ Talaka parapọ; ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti dapọ mọ ọmọ Ẹgbẹ Ọlọmọ. Owo ilu gọbọyi ti a fẹ na ko si ẹniti o le bi wa lere kinni a fẹ fi ṣe.

### Isinku Alake

ogb o awọn enia jankan jankan ti nwọn lọ si Abẹokuta nibi isnku Ọba Alake, Ademọla Keji ti o waja ni oṣu kẹta sẹhin ni o kan saara si awọn ọmọloku. Olukuluku wọn ni nwọn jẹ ti nwọn si mu.

Mo gbọ wipe Alhaji (Oloye) D. S. Adegbenro, Ẹkẹrin gbogbo awọn Ẹgba, gba Oloye S. L. Akintola ati iyawo rẹ ni alejo nibi isinku na, a fi awọn janduku ti o fẹ ba ibẹ jẹ fun wọn. Gbogbo awọn ọlọpa ọkunrin ati awọn ọlọpa obinrin lo ri iṣẹ ṣe ni ẹnu ọna Ṣọṣi Ake.

Diẹ lo ku Ogun Ijẹmọ miran ko ba bẹ silẹ. Ọrọ ọlọpa to, to, to. Awọn to mu awọn ọlọpa lọwọ lọ si ibi isinku na ko ṣe buruku.

### Ijo Kete

Gbogbo yin ti ẹ ri bi ijo-kete awọn Ẹgba ti duu to nibi aṣeyẹ isiku Alake ni lat mọ wipe o yẹ ki a wa ọna ti a o fi ma wa ilọsiwaju ijo na pẹlu ege-dida nitoripe awọn ọmọ Ẹgba aiye isisiyi mọ lati ma wo ijo - Kete ni, nwọn ko le jo o. O yẹ ki awọn ọmọ Ẹgbẹ ṣe paramu lati kọ orin ere wọn na sinu redio.

### Loya Oba

Mo ba ọrẹ mi "K K", Ọgbẹni Arẹmu Kọtun yọ un Oye Lọya Ọba (Q C) ti nwọn fi jẹ ni ọsẹ yi pẹlu Ọgbẹni Charles Syngle. Bẹni, bi ori ba pẹ nilẹ a di orire. Gbogbo yin ni mo ba yọ, emi na si mbọ wa ba nyin ṣe ajọyọ na ni ẹkunrẹrẹ.

### Enahoro

Ọrọ Oloye Anthony Enahoro, igbakeji baba ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o lọ sa di awọn alaṣẹ ilu Gẹsi di egungun ba awọn kan lọna ọfun. O mbọ loni, o mbọ lọla, awọn ogunnagbongbo ilu Oyinbo si ni ki o duro na. Oloye Enahoro, mo gba dun rẹ.

### Flora

Mo gbọ wi Ọlọla Flora iyawo Gomina-agba Nnamdi Azikiwe ni yio lọ ṣe aṣoju ọkọ rẹ ni ibi iyawo iyekan Ọba ilu Oyinbo ninu oṣu ti mbọ. Mo gbọ wipe ti nwọn ba si ti ṣe iyawo na tan, on na yio duro diẹ fun igbadun ni ilu Oyinbo ki o to wa si ile.

### Mayo Saro

Ki nto par ọro iregbe mi ti ọsẹ yi, o yẹ ki nki alejo wa Ọlọla A F Rahman, Mayọ ilu Freetown ni Saro ti o wa bẹ wa wo ku abọ. Mo gbọ wipe iran Ẹgba ni Abẹokuta ni awọn ti o bi Mayọ na. Mo gba ni imọran ki o fi ọsẹ kan dele ni wiwa ti o wa si Nigeria yi, bi o ba jawe ara rẹ daradara o le ri awọn ibatan rẹ.



Oloye S. L. Akintola

**Aworan yi ni ti Oloye Samuel Ladoke Akintola ti ṣe Olotu Ijọba Ipinle Iwo Orun ti o lo ba won se aseye isinku Oba Alake ni Abeokuta laipe yi.**

**Davey Moore Elese Ku**

# Gomina Kan Ni On Ko Fe Ere Ese Mo Ni Ilu On

(O bere leju ewe keta)

Ni ijeta, agbo pe awọn aṣofin ara ilu Carlifonia ni Amẹrika ti gbe iwe asọtẹlẹ kan jade wipe awọn fẹ ṣe ofin ti ko ni jẹ ki nwọn mọ ja ija janduku na mọ.

Pope John ni ilu Rome ni o yẹ ki awọn ara ilu on ro ọrọ na se. paapa on ko fẹ ija ẹṣẹ mọ. Ija ọmọluwabi kọ, ija ẹranko ni.

Onirohin wa ni gbara ti nwọn ti ja ija ẹṣẹ na tan ni Moore ti ni ori nfọ oa, ti nwọn si gbe e gba ile iwosan kan ti nwọn npe ni White Memorial Hospital lọ, ọpọlọpọ awọn ogunagbongbo dokita ni nwọn si lọ sibe lati gba ẹmi rẹ la, kaka ki o san nṣe ni aiperi tubọ wọ ọrọ rẹ.

Jinni-jinni ba Iyawo rẹ paapa ti o nlọ wo o nibiti nwọn gbe tẹ ẹ si ni ile awọn alaisan na, ti o fi de ibi ti nwọn ni lati ma tọju iyawo rẹ na.

Lati ijarun ti Moore na ti jalaisi ni gbogbo awọn enia kakiri agbaiye ti ntẹ waya ibakẹdun si iyawo ati awọn ọmọ rẹ.



Hogan King Bassey
Abi Ese Kun bi Ojo

## Ramos sokun lori oku Moore

Sugar Ramos, olori awọn ajẹṣẹ featherweight ti o ṣẹṣẹ gba ipo na lọwọ Moore paapa ko le lọ si ilu rẹ mọ nigbati o gbọ wipe ẹniti to'n pẹlu rẹ jọ ja ko jẹ ara aiye ko jẹ ero ọrun mọ.

Nṣe ni o lọ joko si inu hotẹli ti o de si ki nwọn to ja ija na ti o ngba adura lọsan loru wipe ki Ọbgẹni Moore le ru u ye.

Ki Moore to jalaisi, Ramos lọ si ile alaisan ti Moore wa, nigbati o foju kan iyawo Oloogbe na nṣe ni o (Ramos) bu sekun, ti o nke bi ọmọ kekere.

A gbọ wipe o ti ju adọtalenirinwo awọn enia ti o ti ku nigbati nwọn ti bẹrẹsi fi ere janduku yi ṣe ere-ije ni agbaiye; enia mẹta ni ọmọ Nigeria ti nwọn ja ẹṣẹ ti nwọn ku-awọn na ni Ọgbẹni Panapana kan, Ilọri ati ẹnikan l'Eko.

## A-gun-to-aso-lo ge eran ara re ku

STOCKHOLM — Ọgbẹni kan ti o fi ẹsẹ bata meji pẹlu ẹsun mẹrin ti awọn ẹgbẹ rẹ npe ni a-gun-to-aṣọ-lo ni gigun on na su on. Ọgbẹni a-gun-to-aṣọ-lo, o ni ki nwọn ba on ge ẹran diẹ-diẹ ku ninu awọ ẹran on.

## E ka

**Iwe Irohin ELETI-OFE ti o kun fun Irohin Aladun ati Ogbon losose.**

## Awon Egbe Alakuko Ibadan se Iranti Adelabu

IBADAN — Ni ijarun ọjọ Aje tiṣe ọdun karun ti Alhaji Adegoke Adelabu Olori alatako ti o jalaisi ninu janba mọto lorita meta oju ọna Ode-Omu, ni awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Alakukọ (NCNC) ṣe iranti oku rẹ Nkan ti gbogbo wọn kọ se ni pipe ti gbogbo awọn ni owurọ kutukutu si ojude ile Ọgbẹni Adeoye Adisa ni Ọja Igbo.

### Ile Wiwo

Lẹhin eyi nwọn to lọwọ lọwọ lọwọ lọ si Oke Oluokun ni agbo'le Oloogbe Adelabu na. Nibẹ ni Ọgbẹni Adisa ti bẹrẹsi sọ nkan nla ti Ijọba aladapọ ti awọn nṣe nisisiyi yio ṣe fun ilu Ibadan.

Ọgbẹni Adisa ni ki o ma ṣe ya awọn ara Ibadan lẹnu lati gbọ wipe Ijọba nṣe eto lati tun ilu Ibadan ṣe nitori eyi ọpọlọpọ awọn ile kẹgẹkẹgẹ ni nwọn yio wolulẹ, ti nwọn yio si tun gba ilẹ o ni Ijọba yio si sanwo ilẹ ti nwọn ba gba na, nwọn yio si tun ba wọn wa ibiti o ba dara lati kọ ile si.

O ni bi Ijọba ba ṣe eyi tan awọn ara Ibadan paapa a ri wi... a di ilu imọtoto,

# New Senior British Trade Commissioner In Nigeria Appointed

LONDON — The British Board of Trade announce that Mr. C E Dymond, lately Principal British Trade Commissioner in Kenya, has been appointed Senior British Trade Commissioner in Nigeria. He is expected to take up his appointment early in April in succession to Mr. D. G. Stewart-Smith, who is returning for duty with the Board of Trade.

Mr. Dymond, who is 46, entered the Civil Service in the Board of Trade in 1946. Since 1951 he has served as British Trade Commissioner in Africa. He was educated at Tiverton Grammar School and the University College of the South West and has a London B. Sc. degree in Economics (Hons).

During the war Mr. Dymond, served with the Royal Artillery in France, Norward, West Africa, India and Burma and attained the rank of Major. He has four children, two girls and two boys; only his youngest daughter will accompany her parents in Nigeria.

## Government Offer Amnesty To Sudanese Refugees

SUDAN — The Ministry of Interior in an official statement recently offered Amnesty to all those who fled the Republic of the Sudan as a result of the 1955 Disturbances.

The statement read in part: "In order to gratify the aspirations of these Southern citizens who field from the Sudan during the 1955 disturbances and who are now anxious to return home and since it is the great concern of the Revolution Government to enable them to be reunited with thier families the council of Ministers has decided to grant Amnesty to all Southerners who crossed the Borders to neighbouring countries.

This Amnesty will include all those who escaped since the Riots of 1955 Those who are tried in Alsentia and who are still wanted for trial on certain charges connected with the said Disturbances with the the excention of Murder Charges".

### Also Prisoners

During the Holly Ramadan Bairam Feastival, the Government of the Republic of the Sudan, granted a general Amnesty to all prisoners who were sentenced to prison terms as a result of the 1955 mutiny in the Southern Provinces.

## Lagos Dentist on London Fellowship Course

LONDON—Mr. J. R. Ana, former dental surgeon at Lagos General Hospital, is hoping to become the first Nigerian to qualify as a Fellow in Dental Surgery at the end af his studies in London, in July.

From Calabar, Mr. Ana is now gathering as much operating experience as he can before sitting the exams at one of British's leading centres for dental surgery- the Eastman Dental Hospital in London. He is studying under Nigeria/U.K. technical assistance arrangments.

"I am working with some of the most distinguished oral surgeons in the world," said Mr. Ana, who performs several operations every day, besides attending on others.

"Oral surgery is s yet unpeveloped in Nigeria and Ian hoping when I return home to interest the Goverment in setting up a special department for the subject at the University of Lagos," he added.

"Such a department could do a tremendous amount to counteract the worst effects of gun decad, which is as common in West Africa as caries is in Europe but often has much more serious consequences. I could also do much work iu correcting congenital abnormalitise, such as cleft palate, hare lip, and diseases of the facial bones and muscles."

# Local Hoteliers Form New Union

LAGOS--A group of hoteliers and caterers from all over Nigeria have formed an association called- The Hotel and Catering Association of Nigeria. Membership includes hotel owners, managers, staff of hotels and catering establishments.

The principal aims of the association include developin the standard of hotels and catering institutions in order that they may play a leading and important role in promoting the commercial, business and tourist development of the country. It will also assist in promoting facilities for the training and advancement of staff in the industry.

At the inaugural meeting held over the weekend in Lagos, a steering committee, to progress the formation of the union, was elected. Among those who attended the launching ceremony were representative from the ministries of Commerce and Industry, Education and Labour

## London Boxing Promoter Hopes to Stage Tiger-Fullmer Fight in Nigeria

LONDON—London Boxing promoter JackS olomon who arrived Nigeria on Thursday, 28 a March with high hopes of staging a return fight between Nigeria's world middleweight champion Dick Tiger and American Gene Fullmer in Nigeria later this year.

I am here in Nigeria at the invitation of the Federal Government, Solomon said yesterday, Dick Tiger, his manager Jersey Jones and his European agent Booby Diamond I shall discuss fight arrangements with Federal and Regional Ministers responsible for sport.

It is too early to say where in Nigeria the fight will be staged, but I am confident that it will take place, he added.

Read And Advertise In Eleti-Ofe

Weekly News Paper

## Dick Tiger de !



Aworan yi ni ti Ọgbẹni Dick Tiger, ọmọ ilu Nigeria ti awọn ara ilu Amẹrika ni nṣe ni ẹṣẹ re nku bi ojo, nigbati o de lati ilu Amẹrika; iyawo re ti o wa lati Aba wa pade re ni Ikẹja ni o wa lẹgbẹ re yi. Awọn ara Eko ṣe ẹyẹ nla fun un ni ọdan l'Eko iọjọ ti o wọ ilu lẹhinti o ti bori ẹlẹṣẹ kan ti nwon n a ni Gene Fullmer tan.

## Oba Kano Binu Fi Lawani Oba Sile

( O bẹrẹ loju ewe kinni )

owo si ko ye awọn si ni nwọn ba yan Oyinbo kan ti orukọ rẹ njẹ D.I. Muffet lati ṣe iwadi (ẹnkuari) bi ọrọ Ijọba Ibilẹ na ti nlọ si ati pe ki ni nka ti awọn le ṣe lori gbogbo rẹ.

Ọrọ ẹnkuari Ijọba Ipinlẹ ilu Kano na fẹ bi ige bi adubi nigbati nwọn kọkọ bẹrẹ si ro ẹjọ ẹnkuari na.

### Omo Oba

Ninu nwọn bẹrẹ iwadi na lọwọ ni nwọn da awọn diẹ ninu awọn ọga ile iṣẹ Ibilẹ Ijọba na duro lẹnu iṣẹ, ninu rẹ na ni nwọn tun wa ọmọ Ọba na kuro nilu wa si Eko. Larin ọrọ na ni a gbọ wipe owo ko si ni apo Ijọba Ibilẹ rara lati fi san owo awọn oṣiṣẹ wọn. Awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni nwọn wa ọnakọna lati san owo oṣu fun awọn oṣiṣẹ ti nwọn mba Ijọba Ibilẹ Kano ṣiṣẹ.

### ỌLỌPA'NU MU ALIKALI KANO

ri ọrọ ilu Kano.

Awọn alamojuto Ijọba Ariwa ni bẹ awọn si ti ṣe ikilọ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ fẹjumọ ẹnikẹni ti o ba sọrọ gẹgẹbi ẹlẹri nibi iwadi ọrọ ilu na.

Bi nwọn ba ti ṣe ọrọ na si, ẹ o ma gbọ lọdọ onirohin wa lọsẹ ti mbọ.

Ọgbẹni Muffet ti o ṣe iwadi ọrọ Ijọba Ibilẹ Kano na ti gbe iwe iyọr nkan ti o ri nipa iwadi na fun awọn alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Kaduna, lati bi ọjọ mẹta ni nwọn si ti nṣe ijiroro lori iwe na ṣugbọn nwọn ko ti gbe abayọri iwadi na sita fun gbogbo agbaiye ri.

Onirohin wa ni on gbọ wipe lori ọrọ abayọri iwadi yi ni Ọlọla Kashim Ibrahim, Gomina Ipinlẹ Ariwa fi pe Ọba na ni Kaduna lati ba da imọran.

## Ijoba Apapose Bere Ipade Igbimo

(O bẹrẹ loju ewe kejọ)

### Olopa Tuntun

Eyi ti o jẹ pataki ninu ọrọ Gomina-agba na ti o sọ ni ti ẹru jẹjẹ ti o nba awọn alakoso Ijọba kakiri ipinlẹ Nigeria fun gbogbo bi nkan ti nlọ si ni ni ilu nisisiyi. Gomina ni awọn si ti mura tan lati gba awọn ọlọpa tuntun jambu[illegible] n[illegible] aw[illegible] ko fẹ [illegible] awọn jandu[illegible] enie fi [illegible] se awọn [illegible] nu awọn [illegible] ti ọta [illegible]

### Egbe Osise

Gomina-agba ni Ijọba fe gbe [illegible] kan jade laipẹ yi lori awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ ilẹ Nigeria ti awọn ajọ kan ma n fun wọn ni ẹbun owo lorişirisi ni aburadi, nwọn ni gbogbo nkan ẹbun owo bayi ni Ijọba fe mọ bi o ti se nwọ'le fun wọn.

Nwọn ni awọn fe tun ofin atijọ ti awọn ti ṣe lori awọn ẹgbẹ osise (Trade Unions) ilu Nigeria ṣe, ki awọn si wa ona lati ka awọn ọmọ ẹgbẹ osişe na lọwọ ko ni ona ti o tọ ati ti o y-

### Kereni Tuntun

Gomina-agba na ninu ọrọ re fi ẹnu kan eto lati ko kereni miran ti yio fi jẹ [illegible] ti awọn eto yio ma gba wọ ilu Eko, eleyi yio si din wahala awọn moto ti ko nri ọna gba ku.

Ọlọla Azikiwe ni Ijọba ti tun ṣe paramu ati [illegible] eto ọkọ ilẹ (Railway) ati ọkọ-ofurufu se.

### Ilu Ajoji

O ni nipa irẹpọ awọn pelu awọn aladugbo awọn ni ilu Afirika ati Malagasy awọn Olotu Ijọba ti ṣe tan lati tun iwe adehun ti gbogbo awọn apejọ ijoko ipade nla na jọ lọwọ si nigbati nwọn jọ pade l'Eko ni ọdun ti o kọja ṣe.

### Ile Eko

Nipa ile-ẹkọ, Gomina ni Ijọba yio sa agbara lati tun ile-ẹkọ ti nwọn npe ni Yaba Technical Institute ṣe ki awọn ọmọ Nigeria le ma ri ibi kọ iṣẹ-ọwọ.

Nipa ilera awọn ara ilu, o ni awon tun fẹ kọ ile iwosan kekere mejọ si ilu Eko ati ile ti nwọn yio ti ma ṣe iwadi egbogi siwaju si.

### Ile Ejo

O ni awọn yio ṣe eto fun awọn adajọ kotu-ọlọpa. Nipa kotu-nla awọn yio kọ ile mọ eyiti o ti wa nilẹ ti nwọn ti ngbọ ẹjọ ri.

### Lori Redio

Gomina na ni awọn ti ranṣẹ fun ẹrọ kan ti o lagbara ti awọn yio ma lo fun ẹrọ asọrọ-magbesi (redio) ti awọn ara ilu ajoji yio fi ma gbọ ọrọ awọn nibikibi ni agbaiye.

O ni awọn tun wa ni idi eto lati da ile iṣẹ ti awọn yio ma fi irohin ranṣẹ kakiri agbaiye silẹ.

### Awon Minisita

Gomina-agba ni ki ọdun yi to pari gbogbo ibi iṣẹ awọn Minisita ilu Nigeria ti Apapọse ni ilu Eko ni awọn yio si tun eto iṣẹ wọn to ni ikọkan, awọn yio si tun da awọn ile igbẹjọ meji silẹ ni Calabar ati Port-Harcourt nibiti awọn yio ti ma ṣe ẹjọ awọn onifayawọ ti nwọn ko ẹru fayawọ wọle lati Fanandopo.

Nwọn si mba ipade na lọ lọwọ lọwọ nisisiyi.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street Lagos Box 467 Phone 23370 Editor, (Olotu) Ola Onatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.